# IGBEYAWO ỌDỌ-AGUTAN

## Ifihan 19:1-21

## ẸKỌ 464 --- FUN AGBA

**AKỌSORI: "Lãrin ọganjọ, igbe ta soke, wipe, Wo o, ọkọ iyawo mbọ̀; ẹ jade lọ ipade rẹ̀" (Matteu 25:6).**

**I Orin Halleluya ni Ọrun**

1 Ẹgbẹ́ akọrin Ọrun n kọrin iyin si Ọlọrun fun idajọ ododo Rẹ̀, Ifihan 19:1-3
2 Awọn agba ati ẹda alaaye n juba Ọlọrun pẹlu, Ifihan 19:4

**II Ase-Alẹ Igbeyawo**

1 Iyin ti o ga ju lọ fun Ọlọrun lati ọjọ iwa wá yoo ṣẹlẹ nigba ti a ba kede Ase-Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan, Ifihan 19:5, 6
2 Aya Ọdọ-Agutan ti mura tán a si wọ̀ ọ́ ni aṣọ funfun, Ifihan 19:7, 8;Matteu 25:3, 4, 7
3 Ibukun ni fun awọn ti a pe si igbeyawo naa, Ifihan 19:9;Matteu 25:10
4 Angẹli naa kọ̀ ki a foribalẹ fun oun, Ifihan 19:10

**III Ẹgbẹ́ Ogun lori Ẹṣin Funfun**

1 Jesu Kristi ni n ṣaaju awọn ogun Ọrun, Ifihan 19:11-16
2 A pe awọn ẹyẹ oju ọrun lati wa jẹ ẹran ara awọn ti a o pa ninu Ogun Har-magẹddoni, Ifihan 19:17, 18;Esekiẹli 38:17-20
3 Gbogbo apapọ awọn agbara buburu kó ara wọn jọ fun ogun naa, Ifihan 19:19;16:16
4 Iṣẹgun Ọdọ-Agutan naa pari, Ifihan 19:20, 21

## ALAYE

A wà ni Akoko Ẹmi Mimọ́. Ọlọrun ti rán Ẹmi Rẹ̀ sinu ayé lati wá Iyawo kan rí fun Ọmọ Rẹ̀. Nigba ti iyawo ba ti mura rẹ̀ tán, ti aago Ọlọrun ba si yi de wakati ti Oun ti pinnu, Ọkọ Iyawo, Jesu Kristi, yoo fara hàn ninu ofuurufu loke lati mú Iyawo Rẹ̀ lọ. Nigba naa ni Ase-Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan yoo ṣẹlẹ ninu awọn ọrun nigba ti Ipọnju Nla yoo ṣẹlẹ nihin lori ilẹ ayé. Abajọ ti ẹkọ wa fi n sọ fun wa pe, "Ibukún ni fun awọn ti a pè si àse-alẹ igbeyawo Ọdọ-Agutan."

Eto Ọlọrun fun irapada ati ibalo Rẹ̀ pẹlu eniyan ti ṣipaya lati ọjọ ìwà. A ti ri imuṣẹ ọpọlọpọ ninu awọn asọtẹlẹ Ọrọ Ọlọrun. Ọlọrun rán Ofin ati awọn wolii; nigba ti akoko kikún si de, Ọlọrun rán Ọmọ ti Rẹ̀ lati jẹ́ etutu fun ẹ̀ṣẹ wa. A kọ̀ Ọ, a kan An mọ agbelebu, O si jinde ni ọjọ kẹta, O si joko nisisiyii ni ọwọ ọtun Ọlọrun, O n bẹbẹ fun wa. Gbogbo iwọnyi jẹ́ ara eto Ọlọrun lati atetekọṣe, wọn ki i si ṣe pe Ọlọrun ṣẹṣẹ n ṣe atunṣe ohun ti o ti gbèrò fun igbala eniyan. Apa kọọkan ninu eto fun iran yii ni a ti muṣẹ kò si ni pẹ́ pari.

Awa ti a wà ni akoko yii lati ọjọ Pẹntikọsti ni anfaani ti o ga ju ti ẹnikẹni ti o ti lọ ṣaaju wa, nitori a ti gbọ́ ipè Ẹmi Mimọ́ bi O ti n lọ kaakiri gbogbo ayé ti O n wá Iyawo fun Ọmọ Ọlọrun. A ti ri itujade Ojo Arọkuro sori oko ikore pipọ́n. Pupọ ninu awọn wolii ati awọn ẹni yiyẹ igba nì ni wọn ti n fẹ ri nnkan wọnyii ti awa ni iriri rẹ̀, ṣugbọn oju igbagbọ nikan ni wọn fi n ri wọn bi ohun ti n bọ̀ wá. O si wà lọna jijin ni igba naa. A ti ri itujade Ẹmi Mimọ́ ti a fi wọ awọn ti a ti gbala ti a ti sọ di mimọ́ ti wọn si n ṣafẹri wiwá Oluwa. Wọn fi ara wọn si ipo imurasilẹ nipa ririn ninu imọlẹ Ọrọ naa ati nipa gbigba ihamọra ti Oluwa ti pese silẹ.

**Awọn Wundia Ọlọgbọn ati Alaigbọn**

Ninu Matteu ori kẹẹdọgbọn a ri ẹkọ iyanu lori mimura lati ni ipin ninu Ase-Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan. Owe wundia mẹwaa naa fi aworan ti o hàn kedere yé ni nipa awọn marun-un ti wọn mura silẹ fun bibọ̀ ọkọ iyawo ati awọn marun-un ti ko si ni imurasilẹ. Gbogbo wọn jọ wa pọ ni, ṣugbọn a mu awọn ọlọgbọn kuro laaarin awọn alaigbọn, wọn si wọle ki a to ti ilẹkun. Bẹẹ gẹgẹ ni a o ṣe gbé Iyawo Kristi, awọn wọnni ti wọn ba ṣe tan lati gun oke nigba ti Jesu ba de lati mu wọn kuro laaarin awọn ti o yí wọn ka. Pe a mọ̀ pe Oluwa fẹrẹ de nikan ko le fun wa ni iwe ẹri lati ba A lọ. Kiki awọn ti wọn ni Ororo ninu kolobo pẹlu fitila wọn ni yoo le lọ.

Yoo ti pẹ ju lati mura nigba ti ọrọ yii ba ti dun: "Wo o, ọkọ iyawo mbọ̀; ẹ jade lọ ipade rẹ̀." Wiwá Oluwa fun Iyawo Rẹ̀ yoo yara bi manamana ti n kọ lati ila-oorun de iwọ-oorun, yoo si jẹ ni wakati ti a ko reti pe yoo de, nitori Ọrọ naa sọ pe, "ni wakati ti ẹnyin kò rò tẹlẹ li Ọmọ-enia yio de." A o ti ilẹkun.

**Ẹgbẹ́ Akọrin Ọrun**

Orin didun ti a kọ daradara maa n gbadun mọ́ eniyan pupọ ninu ayé lọjọ oni, wọn a si maa ba gbogbo eniyan sọrọ bi o tilẹ jẹ pe ẹya wọn tabi ilu-ibilẹ wọn yatọ si ara wọn. Adun orin jẹ nnkan ti n gbé idahun alayọ dide ninu ookan àyà wa. Ṣugbọn ohun Orin Halleluya ti Ọrun yii ni yoo jẹ ẹkunrẹrẹ ju lọ ninu gbogbo iyin ti o ti jade lẹnu eniyan ri, ti a ti n kọ lorin ri, tabi ti a ti kọ sinu iwe lati ọwọ́ awọn eniyan mimọ́ Ọlọrun lati ọjọ iwà wá. A n kọrin nipa Rẹ̀ nihin, ohun ti O ti ṣe, pe Oun yoo pada wá ati ohun ti Oun yoo ṣe; ṣugbọn orin yii, yala a kọ ọ lorin ni tabi a sọ ọ lọrọ ni, yoo dún jade lati ẹnu ọpọ awọn eniyan ni Ọrun, awọn wọnni ti a si gbà soke sinu ofuurufu lati wà pẹlu Oluwa lae yoo si gbadun rẹ̀. Iru orin wo ni yii! A kò fẹ padanu rẹ̀.

**Igbeyawo**

Ki i ṣe olukuluku ẹni ti a ba gbala ni ikẹyin ti o si lọ si Ọrun ni yoo ni ipin ninu Ase Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan. Ko yẹ ki eyi mu ẹnikẹni rẹwẹsi lonii, nitori anfaani wà fun gbogbo eniyan lati mura nisisiyii lati jẹ́ apa kan ninu Iyawo Kristi. Eniyan ko le fà sẹyin kuro ninu imọlẹ ti n tàn ni akoko ti rẹ̀ ki ẹni naa si lọ lai jẹbi; nitori naa o jẹ́ anfaani ati ojuṣe olukuluku Onigbagbọ́ lonii lati rin ninu gbogbo imọlẹ ti o ṣe e ṣe fun un lati ni. Ọlọrun ko ni ṣe idajọ awọn ti igba laelae bi yoo ti ṣe ti awọn ti igba isisiyii; nitori naa o dara fun olukuluku nisisiyii lati lo anfaani ipese ilana Ọlọrun ki o si ri igbala, isọdimimọ́, ati ifi Ẹmi Mimọ́ ati iná wọ ni, ki o si maa rin ninu gbogbo imọlẹ Ihinrere.

A sọ ọ tẹlẹ lati ẹnu Wolii Joẹli pe: "Yio si ṣe, nikẹhìn emi o tú ẹmi mi jade si ara enia gbogbo; ati awọn ọmọ nyin ọkunrin, ati awọn ọmọ nyin obirin, yio ma sọtẹlẹ, awọn arugbo nyin yio ma lá alá, awọn ọdọmọkunrin nyin yio ma riran: ati pẹlu si ara awọn ọmọ-ọdọ ọkunrin ati si ara awọn ọmọ-ọdọ obirin, li emi o tú ẹmi mi jade li ọjọ wọnni" (Joẹli 2:28, 29). Dajudaju igba ikẹyin ni akoko ti a wà yii, a si ti ri imuṣẹ asọtẹlẹ yii ninu iran ti wa. Eyi yii ni Arọkuro Ojo ti a fi fun ni lati pese Iyawo Kristi silẹ. Kò wà fun awọn diẹ ti a yàn nikan, ṣugbọn fun gbogbo eniyan, ọkunrin ati obinrin, ọmọ-ọdọ ọkunrin ati ọmọ-ọdọ obinrin (eyi n fi ye ni pe o wà fun ọlọrọ ati talaka bakan naa). Nigba ti Ọlọrun n bá Israẹli lò ni ọjọ wọnni O bá wọn lo gẹgẹ bi eniyan ọ̀tọ, awọn iranṣẹ wọn lati orilẹ-ede miiran kan ni anfaani gẹgẹ bi ọmọ-ọdọ ni. Ṣugbọn nisisiyii ẹnikẹni ti o ba fẹ le jẹ ọ̀kan ninu Iyawo Kristi.

A ko mọ̀ gbogbo ohun ti yoo ṣẹlẹ nibi Ase Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan, ṣugbọn a mọ̀ pe Iyawo yoo wà ni isopọ laelae pẹlu Ẹni ti O wu ọkan rẹ̀ patapata (Orin Sọlomọni 5:16); Ẹni ti O fẹ ẹ fun ara Rẹ̀ (Hosea 2:19, 20); Ẹni ti o wi pe: "Emi nlọ ipèse àye silẹ fun nyin … Emi o si tún pada wá, emi o si mu nyin lọ sọdọ emi tikarami" (Johannu 14:2, 3); Ẹni ti o fi ifẹ Rẹ̀ si ijọ Rẹ̀ hàn nigba ti O gbadura pe, "Ki gbogbo nwọn ki o le jẹ ọ̀kan; gẹgẹ bi iwọ, Baba, ti jẹ ninu mi, ati emi ninu rẹ, … ki ifẹ ti iwọ fẹràn mi, le mã wà ninu wọn, ati emi ninu wọn" (Johannu 17:21-26); Ẹni ti Iyawo jẹ oloootọ si, ti o n gbadura ti o si n ṣowo titi Ọkọ rẹ̀ yoo fi tún pada wá si ayé (Owe 31:10-31). O n ṣe ohun ti ọwọ́ rẹ̀ ri ni ṣiṣe, o si n ṣe e bi fun Oluwa. Anfaani-kanfaani ti Ọlọrun ba fun un ni o n lò pẹlu itara ati agbara, bi ẹni pe Oluwa Jesu Kristi sọ fun un pe "Ṣe e," ti O si duro nibẹ ti O si ṣọ ọ titi iṣẹ naa fi pari; ki i ṣe lati wu eniyan, ṣugbọn bi ojuṣe ti Kristi n reti lọwọ rẹ̀ ti yoo si san ère rẹ̀ fun un. A o ṣe Iyawo ni ọ̀kan pẹlu Oluwa, Ọkọ rẹ̀, "Nitori Ẹlẹda rẹ li ọkọ rẹ; OLUWA awọn ọmọ-ogun li orukọ rẹ̀; ati Olurapada rẹ Ẹni-Mimọ Israẹli" (Isaiah 54:5).

Kristi funra Rẹ̀ ni yoo ṣe Iranṣẹ fun awọn eniyan Rẹ̀ nibi Ase-Alẹ Igbeyawo, awọn eniyan si ro pe ni akoko yii ni a o pin ere fun ijolootọ fun iṣẹ-isin. Bi o ti wu ki eyi jẹ, dajudaju eyi jẹ akoko ti o yẹ lati maa fi oju sọna fun lati gba ibukun ologo.

**Ipari**

Lẹyin Ase Alẹ Igbeyawo Ọdọ-Agutan, ati ni ipari Ipọnju Nla nihin lori ilẹ ayé, Oluwa yoo pada wá ninu agbara ati ogo nla. O wá lakọkọ ni irẹlẹ ati itẹriba ṣugbọn ni akoko yii yoo wá lati ṣe idajọ lori awọn ti wọn pa awọn wolii ati awọn ẹni iwa-bi-Ọlọrun. Eyi ni a n tọka si gẹgẹ bi Ifihan Rẹ̀, ifarahan keji labẹ bibọ̀ Rẹ̀ lẹẹkeji. Ifarahan Rẹ̀ lẹẹkinni ninu awọsanma ni lati pe Iyawo Rẹ̀ wá si Igbeyawo Ọdọ-Agutan. Iba awọn ti wọn ti pa aṣọ wọn mọ́ ni mimọ́ ati funfun ni yoo ri I nigba naa. Ni igba ifihan Rẹ̀ Oun yoo gẹṣin wá gẹgẹ bi olori ẹgbẹ́ ogun Ọrun, gbogbo oju ni yoo si ri I.

Oun yoo wà lori ẹṣin funfun, bakan naa ni ẹni kọọkan lara awọn ọmọ-ogun ti n tọ Ọ lẹyin. Nigba naa ni ogun Har-magẹddoni yoo ṣẹlẹ. Eyi yoo jẹ́ ogun ododo, iparun ti yoo si mu wá yoo jẹ́ idajọ Ọlọrun. Kristi yoo

gbé ijọba Rẹ̀ kalẹ lori ayé yii yoo si fi ọpa irin ṣe akoso awọn orilẹ-ède. Eyi yoo jẹ́ ijọba ododo fun ẹgbẹrun ọdun. Ẹranko nì ati eke wolii nì, ti o ti tan awọn ti wọn gba ami ẹranko naa jẹ, ni a o dè ti a o si sọ sinu adagun iná ti n fi sulfuru jó.

Ni igba ifihan Kristi, awọn Ju yoo maa wo Ẹni ti wọn ti gún ni ọkọ, wọn yoo si gba A ni Messia wọn. Wọn yoo maa gbadura wọn yoo si maa ṣọfọ fun Un laaarin igba Ipọnju Nla eyi ti a tun n pe ni igba ipọnju Jakọbu. Itan wọn ti koro to lati igba ti wọn ti kan Oluwa mọ́ agbelebu! "O tọ̀ awọn tirẹ̀ wá, awọn ará tirẹ̀ kò si gbà a. Ṣugbọn iye awọn ti o gbà a, awọn li o fi agbara fun lati di ọmọ Ọlọrun" (Johannu 1:11, 12). Awọn eniyan mimọ́ ti wọn bá Kristi pada, pẹlu awọn ti a ti bẹ́ lori nitori ẹri wọn ni akoko Ipọnju ti a si ji dide, yoo bá Kristi ṣe akoso ati ijọba ni akoko Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun.

Gẹgẹ bi Noa ati awọn ẹbi rẹ̀ ti n mura silẹ ki a le gbà wọn kuro ninu Ikun Omi, bẹẹ gẹgẹ ni Iyawo n ṣe lonii. Awọn eniyan ti o wà yi Noa ká fi eti wọn gbọ́ ṣugbọn wọn kò fi ọkàn wọn moye. Lonii awọn eniyan n gbọ́ ọrọ Ihinrere pe Oluwa n bọ̀ ṣugbọn wọn ko ṣi ọkan wọn paya si ọrọ naa, abayọrisi rẹ̀ ni pe wọn "kò mọ̀" pe Oluwa fẹrẹ fara hàn. Awọn ti wọn n pese ara wọn silẹ ni wọn n ka si "ẹni ti n padanu nnkan pupọ ninu ayé yii," ṣugbọn, ọpẹ ni fun Ọlọrun, eyi naa gan an ni wọn n lakaka fun. Lai pẹ, Oluwa yoo wi pe, "Wá, enia mi, wọ̀ inu iyẹ̀wu rẹ lọ, si se ilẹkun rẹ mọ ara rẹ: fi ara rẹ pamọ bi ẹnipe ni iṣẹ́ju kan, titi ibinu na fi rekọja. Nitorina, kiye si i, Oluwa ti ipò rẹ̀ jade lati bẹ̀ aiṣedede ẹniti ngbe ori ilẹ wo lori ilẹ; ilẹ pẹlu yio fi ẹ̀jẹ rẹ̀ hàn, kì yio si bò okú rẹ̀ mọ" (Isaiah 26:20, 21).

Ẹ jẹ ki a lakaka tọkantọkan lati wà nibi Igbeyawo Ọdọ-Agutan, nigba naa a o pẹlu awọn ti yoo pada pẹlu Rẹ̀ lati ṣakoso ati lati jọba fun ẹgbẹrun ọdun.

**AWỌN IBEERE**

1 Nigba wo ni Igbeyawo Ọdọ-Agutan yoo ṣẹlẹ?
2 Owe wo ni o kọ́ ni ni anfaani ti o wà ninu pe ki a ni Ororo ninu kolobo wa?
3 Ta ni yoo ṣe akoso ayé yii ni akoko Ipọnju Nla?
4 Ta ni yoo ṣe akoso ayé yii ni akoko Ijọba Ẹgbẹrun Ọdun?
5 Ki ni yoo ṣẹlẹ si ẹranko ati wolii eke nì nigba ifihan Kristi?
6 Ki ni yoo jẹ́ ipinnu awọn Ẹgbẹ Akọrin Ọrun ti n kọrin ni Ọrun?
7 Ta ni yoo ni ipin ninu Igbeyawo Ọdọ-Agutan?
8 Ta ni yoo maa ṣe iranṣẹ nibi Ase Alẹ-Igbeyawo Ọdọ-Agutan?